PAGIDARI ! IGI NDA L'OKE - ODE - ILE - IRE !!




AWOGBA
Omode fun
Girl, Eyi,
Hihu - ehin,
Orere.
Ra Tire Ni
Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare
Okebola,
Ibadan.
116, Great
Bridge St.,
LAGOS

ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 42/6d Now 32/6d
Obtainable at :-
A. B. AKINYẸMI
10A, Moloney Bridge St.,
LAGOS.

VOL. VIII No. 450. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, JANUARY 14, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

# IDAHUN SI ORO OGBENI G. A. MAKU, EKO.

Ninu Iwe Eleti-Ọfẹ ti ọjọ Kẹtadilogun oṣu December t'ọdun to koja

Ni akọkọ ọrọ mi, awọn agbalagba ni wọn ma nsọ wipe bi ọmọde ko ba gbọ itan, o ni lati gbọ arọba, ki jwọ Ọgbẹni G. A Maku maṣe sọ ni kọrọ wipe a pẹ pupọ fun esi ọrọ yin ni kunkun ni mo fun yin lesi.

Akọkọ ni wipe iwọ Ọgbẹni G.A. maku ti o ba fẹ lati gbọ ọrọ awọn ti e sọpe o bi ẹ, mo si tun wa mọ daju wipe, iwọ ki iṣe ọmọ Oke-ọdẹ ati pe iwọ ko ri agbalagba to mọ itan ba lo, irọ ti wọn npa fun ẹ lo nsọ sita. Emi yio fi han yin. Njẹ iwọ le sọ fun wa ọgangan ibi ti wọn gbe sin Ọlọla Maku Baba yin si ni Oke-Ọdẹ Agodongbo ti awa loni yi?

Bi o ba jẹbẹ, jọwọ ṣe apejuwe fun wa, ọkankan ibẹ gan, Nipa ọrọ ẹgan tabi lounibini yin ti ẹ sọ niyẹn o. Ẹjọwọ, mo tun fẹ ran yin leti Iwe itan ti ẹ sọpe ki nlọ wa, njẹ, ẹ le sọ orukọ rẹ, tabi ki ẹ sọ ibiti wọn ti nta.

Ẹjọwọ, ẹ ma ṣe fi ṣe ibinu, mo ro wipe, awọn to fun yin ni irohin na sinu iwe, Ki iṣe ara awọn to mọ nipa Iṣẹdalẹ Oke-Ọdẹ Agodongbo ti a wa yi? Bibẹkọ, ẹnyin koni sọ ọrọ irọ pipa wọnyi, ko si si nkan meji, o dabi wipe nisinyi ni awọn ti ko ti lẹ gbọ nipa yin ri, yio wa kọ ẹkọ die, ati pe yio jẹ atọna fun ẹnyin gẹgẹbi ilọsiwaju, ati ikede ara yin ti ẹ fi s'inu iwe ti a darukọ s'oke ọrọ wa, ti a si fun yin ni idahun rẹ.

(koi ti pari)

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ọna tara ti enia legba lati
di oniṣowo nilẹ Nigeria wa,
ni ile ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Ẹnikẹni ti o ba fẹ kan ogunlọgọ
simọye awọn oniṣowo ilẹ Nigeria lara,
yala lati ma ta ọja fun wọn ni,
tabi lati ma ra awọn ohun ọgbin ilẹ wa,
ki o lọ si NATIONAL BANK

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

# Asia Ola Nfe Lele



Nigbogbo asiko ti Alaiyeluwa Ọba Obinrin yio lo si ilu Nigeria wa yi, ile ti ẹ ba ti ri Aṣia ti aworan rẹ mbẹ ninu iwe wa yi, ki ẹ mọ wipe Alaiyeluwa ni o ngbe ile na.

Bi ẹ ba si ri lara Mọto ki ẹ mọ pe eyiti Ọba Alaiyeluwa nlo ni awọn Ọkọ Mọto bẹ.

Eyi jẹ afihan ti yio ma fi ibiti Alaiyeluwa ba wa han fun awa enia abẹ Aṣia rẹ.

## Keke Ko Gbodo Gbin !

Awọn mẹtata Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Alhaji Ahmadu ati Nnamdi Azikiwe ti iṣe alakoso Ijọba wa, Nigeria yi, fi iwe ikede s'ode fun gbogbo ọmọ ẹgbẹ olukuluku wọn, ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) ati ẹgbẹ N.P.C ti Oke Ọya (Northern Nigeria) wipe ki enikẹni maṣe hu'wa jagidijagan nipa ẹgbẹ kẹgbẹ, ki a si da gbogbo ipade akojọ ẹgbẹ duro lati ọjọ kọkanlelogun oṣu January, 1956 yi.

Awọn alakoso wa ṣe ipinnu yi nitori ki o ma ba si ija, rugudu tabi idarudapọ ni asiko ti ao fi pade Alaiyeluwa Ọba Obinrin ilu Oyinbo Gesi, gẹgẹbi o ti wa l'ọkan olukuluku wa lati fi alafia ati ẹyẹ igbadun gba alejo nla na.

Kẹkẹ ko gbọdọ gbin o !

## ERE ẸYỌ ADAMU-ORIṢA FUN ỌBA OBINRIN

Gomina Agba ọlọla James Robertson oloye nla K.C.M.G., K. B. E. ti gba wipe ki a fi ere Ẹyọ Adamu-oriṣa kun awọn ere ti ao fi ṣe ariya yẹ ọba Alaiyeluwa si nigbati o ba wa bẹ wa wo, gẹgẹbi imọran Alaiyeluwa Ọba wa, Adeniji Adele Keji pẹlu awọn isọngbe rẹ fi siwaju Gomina.

Ni ọjọ Alamisi (Thursday) ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu February, 1956, ni ao ṣe ti ere Ẹyọ Adamu-oriṣa na, o si jẹ ọjọ ti Alaiyeluwa ọba obinrin yio fi ilu Nigeria silẹ pada lọ si ilu rẹ. A si ti ya ọjọ na si ọjọ Isinmi gbogbo-gbo.

AGOGORO ẸYỌ,
HU-U-HA-HA.

## Eyi Soju Wa Na

AWẸ-ỌYỌ:- Ni ọjọ kẹtala oṣu kejila ọdun tokọja, (13 12 55) ni Ọlọla Kẹhinde Adeoye Aiyeleru Keji Balẹ Awẹ ṣi Ọja tuntun kan ni oju ọna tuntun lati Awẹ lọ si Oko Ẹlẹiyẹ lọ si ọja Aiyekale.

Lehinti Oludari eto ṣiṣi ọja na–Olcye S.A. Adebiyi Ẹkẹrin Awẹ–fi Alaga ọjọ yi-Ọlọla Kẹhinde Adeoye Aiyeleru keji–sori Aga tan, ni awọn enia bẹrẹ si ṣe adura fun ti ọja na.

A'ufa D A Ọlaọpa, ti iṣe Oluṣọ-aguntan Ijọ Onitẹbọmi kini, ti ilu Awẹ ṣe adura iṣi ọja l'ọna ẹsin ti Onigbagbọ.

Lemọmu ti ilu gbadura l'ọna ẹsin ti Imale Ọgbẹni Ogunronbi-Esinnla gbadura l'ọna ti ẹsin Ibọriṣa. Ṣiṣi ati sisọ ọja na ni orukọ, Balẹ Awẹ, pe orukọ ọja na ni Ajegunlẹ.

Balẹ Awẹ gbadura lori irẹpọ ti awọn ti o ṣe oju Ọna tuntun yi, ti wọn si tun da Ọja sibẹ ni: Awẹ, Ọyọ ati Akinmọrin. O dupẹ pupọ lọwọ wọn, O si tun gba wọn niyanju, lati le tun ma tẹsiwaju ninu ẹmi iṣọkan ati irẹpọ ti wọn ni.

Ọgbẹni J.O. Ọjẹlọla ẹniti iṣe Alaga awọn enia ti o ṣe Oju Ọna ati ọja yi dupẹ Balẹ ati awọn Ijoye pẹlu awọn Igb mọ ilu. Bakanna ni o dupẹ lọwọ awọn gbajumọ ati bọrọkinni ilu ti o wa sibẹ.

Owo iṣi Ọja 1. Balẹ Awẹ, - £2–10s, 2. Awọn ọmọ ile Balẹ-£1 0s 3, Balẹ Oluwatedo-Ọyọ - £1 0s 4, Awọn Oniṣowo Obinrin Awẹ - £2 2s 5. Awọn Ẹgbẹ A ra Koko Awẹ - £2 2s 6, Balẹ K yesi ni Awẹ £1 1s 7, Awọn Olorisa, Awẹ - 5s. Gbogbo rẹ jẹ Pọun mẹwa (£10)

Awọn miran tun da owo ti ao ni an'ani ati ko s'hin.

Larin bi awọn enia ti nmu ẹbun?-ni Balẹ ni Awẹ ki awọn Ọlọja ma ta ọja ki awọn ti nra ma ra, ki awọn onilu m lu ilu, ki awọn onijo ma jo, ki olukuma yọ.

Bakanna ni awọn Ọlọja ba bẹrẹsi ma fun awọn enia ni onjẹ. Iyan a jẹ gbadidi m lu kan ni wọn ra laika awọn ẹran miran.

Ọti ẹmu, ọti ọka, ọti Bia, bẹrẹsi da bi ojo, okudlẹ ko mọ ẹniti ntu l'ọjọ yi.

Awọn enia pataki ti wọn wasibi ṣi ọja yi ni Ọlọla Kehinde Adeoye Aiyeleru Keji, Balẹ Awẹ, Lemọmu Alfa D. A Ọlaọpa, awọn Imale. Onigbagbọ ati abọriṣa, awọn Ijoye ilu Awẹ, Ọmọ-ọba, Lanitẹ, Ọyọ ati awọ Gbajumọ miran.

Ki Ọlọrun alanu jẹki ọja na ṣe gbogbo wa ni rere,

Amin

---

## Adajo Tuntun Fun Kotu Nla.

Ọgbẹni M.C. Nageon de Lestang. ẹniti o ti ṣe ọdun mẹtala ninu iṣẹ ile ẹjọ ni'lu Kenya ni a gbọ wipe Alaiveluwa Ọba obinrin gba wipe ki o jẹ Adajọ ni Kọtu nla ti ilẹ Nigeria.

Ninu ọdun 1947 ni Ọgbẹni Lasting di Adajọ ni ilu Kenya.

---

## Aj'oko Wo Fi Ewon Se Ifa Je.

Agbọ wipe awọn ọkunrin meji ti orukọ wọn njẹ Joseph Daniel ati Pius Musa ni awọn enia meji ti nwọn fi iwe eru (forge tickets) wọ ọkọ ilẹ Reluwe lati ibudo ọkọ-ilẹ, ni Oshodi ninu osu October ti ọdun tokọja.

Nigbati ọrọ yi de iwaju Adajọ Ọgbẹni A. O. Abayọmi ni Kọtu Y ba, ti awọn ọlọpa fi nwọn sun ẹsun wipe awọn ọdaran meji yi ja awọn Reluwe (Nig: Railway Corporation) l'ole nipa fifi iwe eru w'ọkọ Reluwe lati Oshodi wa si Iddo.

Adajọ ju wọn s'ẹwọn oṣu Mejila pẹlu iṣẹ aṣekara. Ẹnyin ọkawe wa, abọ iṣẹ eru re o, nigbati enla tori irin ibusọ mẹjọ (Eight miles) fi ara korin oṣupa mejila 'ọgba onigo.

A SỌ ENIA KUKURU DI GIGUN
Bi Iwọ ba fẹ Gun bi iwọn Esun Meji de Mẹfa. Lo Ilana Titun ti a Ṣẹṣẹ Ṣe.
O DARA FUN
Tọkunrin-Tobinrin.
Olẹ Ni Ao Fi Fun ọ Kọwe Si
ACTIVITIES (D-112)
Kingsway, Delhi-9 India

## Bere-Bere Ki i Sina

— | —

Olotu,

Jọwọ gba mi laye ninu iwe irohin yin Oloyin mọmọ ti o njade ni ọsẹ-sẹ fun awọn ọkawe Eleti-Ọfẹ, lati fi ọna han mi, tabi ki wọn lami loye nipa ibere mi na.

Ibere na jẹ oriṣi mẹta, Ekinni Iwa rere, Ekeji Orire, ati Ẹkẹta Ọrọ ire. Ninu awọn nkan wọnyi, Bi enia ba ni meji ninu nkan wọnyi ti ko ni eyi to le gbeero ninu wọn O ba a jẹ ṣugbọn ko tilẹ ma wa ni meji ninu rẹ, ko wa ni eyọ kan ṣoṣo ninu awọn nkan wọnyi, o ti ko nkan meji to ku pọ mọ, mo fẹ ki ẹ la mi loye kini nkanna ninu wọn

Ibere mi niyẹn o.

Emi ni
S. A. B.
Alias Toff

---

ỌBA ADELE NI YIO GBA ỌBA OYINBO LALEJO

A gbọ irohin wipe ni gẹrẹ ti ọba Obinrin ilu Oyinbo ba ti fi ilu Ọba silẹ, ni ao ti ma gbọ iro gẹgẹbi irin ajo na ti nlọ si. Awọn ọkọ ofurufu m ta ti a npe ni Spitfire ni yio kọkọ ṣiwaju lati ma ṣọ ọna wo, bi ewu ba mbẹ lọna.

Gbara ti ọba na ba ti gunlẹ si Ikẹja. Gomina General ti Eko yio lọ pade rẹ. Lẹhin ti nwọn ba ti pari gbogbo eto tan lọhun, awọn "We yọ mirọ" (Traffic Police ni a npe bẹ) mẹrindilogun yio ṣiwaju mọto ọba yio tẹle wọn lẹhin lẹhinna Gomina ninu aṣọ oye rẹ yio tẹle wọn.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Gehin-gehin

Dan egbogi yi wo fun ẹhin ti o ba di wipe ẹhin ndun enia de ipo ti ko le bẹrẹ, Kindinrin lo fa a Nitoripe iṣẹ Kindinrin ni lati sẹ idọti kuro ninu ẹjẹ ara enia, nigbamiran ẹwẹ ko ni ṣiṣẹ deedee. Ẹhin ti o dun ni jẹ ikilọ fun enia wipe Kidinrin rẹ ko ṣiṣẹ to, o si nfẹ iranlọwọ egbogi De Witts ni a le ro pe o le ṣe iwosan na Nitoripe egbogi na ko ṣe iru iṣẹ bẹ ti ri. Dan wo, lọ ra ọkan ni ṣọbu.



Ohun to da wa loju ni wipe Egbogi DE WITT'S jẹ eyiti a ṣe tonitoni ohun elo rẹ gbogbo lo si mọ.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles

## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS PAINTS, DISTEMPERS, SAFES Etc.
Just Write, Call Or Phone 21372
IKORODU TRADING COMPANY
20/28 BALOGUN STREET (P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD, IBADAN

No.73/S.2/VOL.V/959.

## Classified Advertisement.

The Director of Education, Western Region wishes the following persons to inform him of their present address:-

OGABI, B. E. (A. 23261) formerly a teacher at All Saints' School, Araromi Orita Egbado District.

Thomas, C I. (C. 6/2162) formerly a teacher at Ikosi Central Industrial School, Aghowa.

The Director is anxious to communicate with the above persons in connection with matters pending before the the teachers' Council constituted under the Western Region Education Law, 1954. and which will have to proceed in their absence if they cannot be found.

## Jamba S'ole, Onile Taji

IBADAN. Awọn ole mẹta kan ti ija de nigbati nwọn npin owo ti nwọn ji 'gbe, ni Adajọ ju s'ẹwọn oṣu mẹfa-mẹfa.

Bi ọrọ na ti lọ niyi:- a gbọ wipe awọn ọmọ jaguda mẹta ti ọkan ninu wọn ri owo yọ lara Onișowo kan ni ibudo Mọto ni Ogunpa ti owo na jẹ Ọgbọn ponun ati șile marun (£30 5/-) ni asiko ọdun Keresimesi.

Nigbati awọn meji toku bi lere wipe, elo ni o ba ninu apo na, o sọ fun wọn wipe șile marun pere ni on ri ninu apo. Ni ọjọ kẹta ni ẹniti nwọn ji owo rẹ ri awọn ọmọ Jaguda meji, o si sọ fun wọn wipe ọkan ninu wọn yọ Ọgbọn ponun pẹlu șile marun lara on. Wọn si șe ileri fun wipe awọn yio șe iranlọwọ.

Nigbati nwọn ri Ayikiti ti o ji owo na, o sẹ kan'lẹ, nibẹ ni ija ti bẹrẹ.

Ọkan ninu wọn, Buraimoh Ọlabinjọ lọ sọ fun awọn Ọlọpa.

Nigbati nwọn ko wọn de iwaju Adajọ, awọn ọmọ jaguda na sọ wipe nitori obinrin kan ni awọn șe ja ki ișe wipe awọn ja nitori owo ti awọn ri ji.

Adajọ Ọgbẹni Obisẹsan ju awọn mẹtẹta sẹ'wọn oșu mẹfa mẹfa, ekini, Buraimọ Ọlabinjọ, ekeji, Akintunde Amao, ati ẹkẹta, Jimọ Ajani, Ayikiti Njẹ jamba ș'ole, Onile taji.


## Kere o!

A ti ni orișirisi ogun Germany to șẹșẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS,**

MEDICINE STORES,

7, Egerton Road, Lagos.


No73/S.2/VOL./V.955

### Department of Information Service: Western Region Vacancy for post of Stenographer Grade II.

Applications are invited from suitably qualified candidates who possess the qualifications enumerated below for appointment as Stenographer, Grade II, in the Department of information Services Ibadan.

**SALARY:-** Scale D. 2,3,4. £207 x- £258: £270 x 12-360. £390 x 18-492

**QUALIFICATIONS REQUIRED:-** Candidates should possess a minimum educational qualification of Class VI, Middle or the Cambridge School Certificate, and should show evidence of having passed a standard test (Royal Society of Arts) in Shorthand and typing at speeds of not less than eighty words and thirty-five words per minutes respectively. Officers already in the Service of Government whose educational qualification is lower than Middle VI but who are otherwise qualified and who possess a command of English are also eligible,

**METHOD OF APPLICATION:-** Applications accompanied by copies (not originals) of certificates and testimonials from persons who can speak with authority on your profficiency should be addressed to the Director, Western Nigerian Imfomation Services, Ibadan so as to reach him not later than 11th January, 1956.

Applications from officers already in Government Service should be submitted through the head of the applicants' Department and be accompanied by a Confidential Report on the new Confidential Report Form.

### LAFIA CANNING FACTORY
IBADAN
VACANCIES FOR
A FACTORY MANAGER
& A QUALIFIED CHEMIST

An experienced Factory Manager is required to take charge of all operations at an extensive new factory in Nigeria producing a range of quality products for export in bulk and retail packs. This most responsible post calls for a man of the highest integrity, leadership, initiative, organising and administrative ability, capable of inspiring staff and factory hands with enthusiasm and team spirit. In addition, really good practical experience of all aspects of factory management and hygiene, modern food manufacturing methods and plant, canning processes, etc. is essential; an engineering background would be an advantage.

There is also a vacancy for an experienced CHEMIST (University graduate or member R.I.C.), with practical experience in food manufacture, to take charge of laboratory and be responsible for all analytical and bacteriological work, technical supervision of production and quality of output. Technical proficiency must be coupled with initiative, energy, tact in dealing with laboratory and factory staff.

Application from candidates who have qualifications and experience to be appointed as FACTORY MANAGER and CHEMIST will recieve special and preferential consideration.

Good Salaries and prospects await the right men. Superannuation scheme, houses provided, generous leave, first-class passages for themselves and families. Applications will be treated in strict confidence and must give fullest particulars of all previous experience stating age, family details, date available.

Envelopes should be marked "MANAGER" or CHEMIST,, or "MANAGER/Chemist" as the case may be and addressed to reach LAFIA CANNING FACTORY IBADAN, not later than 25th January, 1956.


## E S'AKIYESI

IGBADUN-OMODE
AWOGBA FUN ỌMỌDE



The Celebrated Fever Mixture and Infants' Preservative
Prevents Sickness, Cures Measles, Fevers, Gripes etc. etc.

Sole Proprietors
PHILIP GBENLE & BROTHERS
6 Balogun Street West
LAGOS NIGERIA

ORIKI IGBADUN ỌMỌDE

Njẹ o ti ra Igbadun Ọmọde fun ọmọ rẹ bi Ogun pataki fun iwosan ọmọde.

Awo ọmọ bi Olodumare, ogun ti abiyamọ ko ri ti o nba ninu jẹ. Abiyamọ ri tan o ndunnu; baba ọmọ bu s'ẹrin.

Igbadun ọmọde ti o ma nda Abiku ọmọ lẹkun anku. A fi gbogbo ile șe ọmọ wẹrẹ. Ko șe mani fun awọn Abiyamọ mi ogun igbadun ọmọde yi jẹ. Tete saro lọ ra igbadun ọmọde ki o bẹrẹ si lo fun ọmọ rẹ, ọmọ rẹ yio si gbadun.

24/- fun mejila (dozen.) 2/6d. fun ọkan each.

LILO OGUN NA :-

Șibi imu tea kan lẹrinmẹta lojojumọ.

IȘẸ RẸ :-

Iba, ọrẹrẹ, igbona, ọka-ori, aiperi, ehin hihu ati orișirisi arun to ma nyọ awọn ọmọde lẹnu. Tọwo, iwọ yio si ri pe rere ni Igbadun ọmọde nșe fun ọmọ rẹ.

Iwọ le ri ogun yi ra ni gbogbo Șọbu ti nwọn nta ogun ni Najiria.

Wholesale Distributor :-

PHILLIP GBENLE & BROTHERS,
6 & 11, Balogun Street West Lagos Nigeria


**Polowo Ọja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ọfe**

# ELETI ỌFẸ

A-NIU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ELETI - ỌFẸ LAGOS"
Phone 23370

VOL VIII. NO. 450. LAGOS, SATURDAY JAN. 14, 1956.


## Bi Ale Yio Tiri, Aro Ni A Ti Nmo

Gbolohun oke wosika wa ọsẹ yi ni o wa si ọkan wa nigbati a ro'nu wa l'ori ohun pataki, ani iṣẹlẹ rere pataki ti yio ṣẹlẹ si ilu wa, Nigeria yi, ninu oṣu ti a wa yi l'agbara Edumare.

Ọlọla nla, Alaiyeluwa Ọba al'Ade, ti ilu awọn Oyinbo Gẹsi ti yio bẹ ilu Nigeria wa yi wo, papa ilu Eko ti iṣe Olu ilu fun gbogbo ilẹ Nigeria, ori rere nla ni eyi jẹ fun wa nitoripe eyi ni yio jẹ akoko ti Ọba al'Ade bi iru eyi yio wa bẹ ilu wa wo pẹlu Ade rẹ l'ori.

Ori rere ti ao ṣe ni ọdun yi ti ṣẹ afi ara han fun ẹnikẹni wa ri s'oju, nitoripe gbogbo opopo ilu wa (Main Roads) ni awọn alaṣẹ ilu wa ti ntunṣe, ti nwọn si nṣe l'ọṣọ, papa Kereni nla (Carter Bridge) ati ọna Ebute-Metta, niwọn igbati ọdun tuntun ba ti bẹrẹ pẹlu ohun rere, apẹrẹ ni eyi jẹ fun awa ẹda enia ti o mbẹ l'ori ilẹ aiye wipe rere ni ọdun na yio jẹ fun wa.

Ki Oluwa Ọlọrun Olodumare jẹki ẹmi gbogbo wa di ọjọ nla na, ki a si ni alafia ara ti ao fi ṣe iyẹsi ti o tọ, ti o si yẹ fun Ọlọla nla, Alaiyeluwa Ọba Obinrin pẹlu Ọkọ rẹ. Ki ọdun yi ko rere owo, rere ọmọ ati alafia fun gbogbo wa.


## LAFIA CANNING FACTORY

IBADAN

### VACANCY FOR SECRETARY/ACCOUNTANT

Applications are invited from suitably qualified persons for appointment to the post of SECRETARY/ACCOUNTANT Lafia Canning Factory, Ibadan.

Applicants must be professionally and impressively qualified and experienced in accountancy and Secretariat practice and have intimate knowledge of cost accounting.

This is an executive post which offers excellent prospects to the right man. The initial Salary will depend upon the applicant's qualifications and experience and will be within the range of £1000- £1500 per annum.

Outfit allowance, Free Medical attention, Provident Fund, House with basic furniture, free passages for wife and children, genereus leave and other conditions of service.

Applications stating qualifications, experience and references should be marked "SECRETARY/ACCOUNTANT" and addressed to reach, LAFIA CANNING FACTORY, IBADAN not later than 25th January, 1956.


## IROHIN ILU OYINBO

IYIPADA DE LARIN WAKATI DIE

(O bẹrẹ ninu iwe wa ọsẹ tokọja)

Ni ọgbọn ọdun s'ẹhin ni [illegible] York [illegible] Elizabeth Alexandra Mary, ni opopo Bruton ni London. Lati igbana titi di ọmọ ọdun mọkanla ni o wa ni idile kẹta ti o ni ẹtọ enia ko si le ni igbagbọ wipe yio tete sunmọ ori tẹ ni si ori itẹ, akoko ti wọn bii.

Ko pẹ pupọ ti gbogbo nkan fi yi biri. Ọdun mẹwa, lẹhinna, ọba George karun ku, aburo ọba yi ko si pẹ ti o fi kọ Ade silẹ, ni oye ba kan Baba ọmọ-ọba yi. Eyi si sọ itan igbe-aiye rẹ di iyatọ lẹsẹkanna, o si di ẹniti o nfi afin ọba ti anpe ni Buckingham palace ṣe ile pẹlu

(Wo yoku ni oju ewe Karun)


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**

*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS



## Department Of Information Service: Western Region.

VACANCY FOR POST OF TRANSPORT OFFICER.

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Transport Officer to one vacancy in the establishment of the Department of Information Services, Western Region.

SCALE OF SALARY : C(T) 1,2. £408 x 18 - £462 x 24- £510. £570 x 24-£618 x 72-£690 x 24-£714 x 30 - 744.

QUALIFICATION : Candidates must have a good general education and some practical experience in transport work. Attainment of a good level of theoretical knowledge and experience of automobile engineering are also desirable.

DUTIES :- The officer appointed will be required to perform the following duties :-

(a) Recruitment and testing of all Departmental drivers.
(b) Allocation of transport.
(c) Regular inspections of all vehicles and supervision and organisation of routine maintenance and minor repairs.
(d) Maintenance of complete vehicle history sheets. These would include petrol and oil consumptions together with records of mileages run, repairs, running and maintenance costs.
(e) To arrange with Public Works Department Workshops for the carrying out of Major repairs.

METHOD OF APPLICATIONS :- Applications should be addressed to the Director, Western Nigeria Information Services, Ibadan, so as to reach him not later than 11th January, 1956.

Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Heads of the applicant's department and be accompanied by a Confidential report on the appropriate confidential report form.

## IROHIN ILU OYINBO
(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

aburo rẹ ọmọ-ọba obinrin Margaret. Agba wa de si on na, gbogbo ohun ti o gbe de ipo yi si han si kedere, ko si pẹ pupọ lẹhin na ti ọkọ ti wọn nfun fi gba ọna miran. Lakotan o di eniti o nkọ gẹgẹbi yio se ni ipo tirẹ ninu ilu nigbati akoko ba to fun lati di olori.

### IṢẸ NINU OGUN AJAKAIYE

Ninu gbogbo ọba Alade ilẹ Gẹsi ko si ẹniti o tii kọ ọmọ rẹ bi ẹniti yio jọba lẹhin rẹ a fi Ọba George kẹfa.

Baba rẹ fun ni ẹkọ atata ti o ye koro, eyi si farahan nisisiyi ninu ọna ti ọba obinrin yi fi ndari awọn orilẹ-ede ti o wa ni abẹ asia ijọba rẹ.

Orisirisi ẹkọ ni wọn fi kọ. Alakikanju ni o jẹ ninu ẹgbẹ ti awọn obinrin ti a npe ni Girl Guides. Lẹhin eyi o kọ nipa ijo, orisirisi ede, eto iṣelu nipa awọn orilẹ ede miran ati ofin.

Ninu ogun, kitakita ni on ati aburo rẹ obinrin nba iṣẹ yi ninu ile-iṣẹ windsor. Gẹrẹ ki o to di ọmọ ọdun mọkandilogun ni o di ẹniti nko aṣọ ogun wọ. Iṣẹ awọn ti o tan ọkọ ṣe ati awọn ti o nwa ọkọ ni o nṣe pẹlu awọn ọmọbinrin miran lati orisirisi ilu ni akoko iṣoro yi.

Lẹhin ogun ni iṣẹ rẹ wa di paraku. Nṣe ni o nkiri lati ma wo awọn ọmọ alainiya ati awọn opo ninu ile ogun, o di alakikanju ninu ẹkọ, o nṣe iya ẹgbẹ fun ọpọlọpọ awọn agbajọ ti o wulo ti wọn dasilẹ, Nigbati o wa de ori itẹ gbogbo iṣẹ wọnyi pẹlu awọn eto ilu wa mu ki ọwọ rẹ kun pupọ.

### IGBEYAWO RẸ L'ARINRIN

Bi iru ọmọ ọba ti ọkan rẹ gbona girigiri fun iṣẹ, ti o si ya igbe aiye rẹ sọtọ bayi, irẹwẹsi iba ba ọkan rẹ ti o ba fẹ ọkọ ti ko nilari. O yan ipin dada, ori rere rẹ si gbe ko ọmọkunrin kan ti o nkọ lati di ọmọ ogun ti oju omi ni ilu ti a npe ni Dartmouth. Ọmọ-alade ti a npe ni Philip, gẹgẹbi ọba Elizabeth keji, jẹ ọmọ-ọmọ ọba obinrin Victoria ati ọmọ alade Albert. Ko pẹ pupọ ti o han gbangba si ọmọ ọba Philip wipe on yio fi Elizabeth ṣe aya.

Irohin ta si awọn obi ọdọmọbinrin alade yi leti, wọn si ri wipe ọmọ awọn fẹran Philip, ṣugbọn ko pẹ pupọ ti iyapa fi de si arin awọn mejeji fun bi oṣu mẹta nigbati ọmọ-ọba Elizabeth ba awọn obi rẹ se irin ajo fun ibẹwo lọ si isalẹ Africa. Ni ọjọ kẹsan oṣu keji ti awọn obi rẹ ti irin ajo ibẹwo yi de ni wọn kede adehun igbeyawo wọn. Wọn ṣe igbeyawo ni ọdun mẹsan s'ẹhin, o si minringindin. Aiye gbọ ọrun mọ, okiki si kan ka gbogbo orilẹ-ede. Igbe aiye awọn mejeji si fi han wipe ọba obinrin yi ni onimọran rere. Eyi si mu ki o de ade ayọ pẹlu, lẹhin Ade ori ite. Ayọ si tan kan inu ọkan rẹ fun ẹbun ọmọ alade meji miran ti wọn wa takọ-tabo. Orukọ awọn mejeji njẹ Charles, ati Anne. Adura wa nipe ki Ade ko pẹ lori ki bata pẹ lẹsẹ.

### OLE KO ILE AS'OFIN

ADO-EKITI A gbọ wipe ole ko ile Ọlọla Z. B. Olokesusi ninu ọsẹ tokọja, ẹru ti nwọn ko nlọ si nkan bi irinwo pọnun. O ti de etigbọ awọn ọlọpa.


*Awọn Ẹbi Ogbe Alayọ sọ wipe*

# OVALTINE

wa fun ilera ati inudidun!





AWỌN ẸBI OGBE ti nwọn gba ẹbun ti apapọ Ẹgbẹ kede sinu "Sunday Times" fun idije awọn ẹniti ẹbi rẹ ba ni inudidun ju ṣe awọn eto inudidun kan ti ko mu inira dani. Jẹ onjẹ atata, sun fọnfọn, ki o ma si ṣe wahala! Bẹni awọn Ẹbi Ogbe nmu OVALTINE lẹmeji lojumọ, larọ ati lalẹ. OVALTINE nfi gbogbo awọn ohun ti o le fun ni ni alafia ati ilera kun onjẹ ti o ba njẹ, o nfun ara ni okun ati idẹra ati igbadun orun. Wa si ji dide pẹlu isọdọtun agbara ati alafia. Ṣe afarawe awọn ẹbi Ogbe, ma a mu OVALTINE nitori ilera ati inudidun.

# OVALTINE

*–ko si ohun ti o dara to!*





OWA 187

## Alailojuti Awo lo nje iyan Obaralofun

LATI ỌWỌ ẸSỌ IKOYI

Awọn Babalawo mẹdogun l'ombẹ nile Ifẹ, Ọrunmila lo ṣe ẹkẹrindilogun awọn Awo Ifẹ. Awọn Awo nwọnyi si ti sa gbogbo agbara wọn nitori ki wọn le soju orunmila de'lẹ ki wọn si rẹhin rẹ, aṣeti ni wọn ṣe.

L'ọjọ kan awọn Awo nwọnyi gbero lati tun ṣe jamba fun Ọrunmila wọn si ti lọ mulẹ pẹlu Ọlọfin, nwọn wa ranṣẹ si Ọrunmila wipe, ki o wa ba wọn ṣe ajọ ase kan loni nile Ọlọfin. Ọrunmila da wọn lohun wipe on mbọ wa.

O yi wọlẹ, o gbe iporua rẹ, o janmọlẹ o ri irẹtẹ-ọkanran fu soju ọpọn, o bẹrẹ si kii bayi wipe:-

Alailojuti Awo lo njẹ iyan Ọbara-lofun,
A difa fun Ọrunmila lọjọ ti a npe gbogbo
Awo jọ sinu ile Ọlọfin,
Lati wa jẹ Iyan Alaimọra, Alaimoju,
A ni ki Ọrunmila gbawẹ ṣulẹ ọjọ oni,
Ọrunmila bere wipe "Esiun tu kan?
Ifa si dahun wipe, Iwọ komọ wipe Alailojuti
Awo lo njẹ iyan? Irẹtẹ ọkanran.

Nigbati Ọrunmila de ile Ọlọfin, nwọn gbe ẹmu siwaju rẹ wipe ki o bu mu o mu aha ti wọn fi nbu ẹmu o bu sinu rẹ o gbe dani, o wọ y lọ su-u; o dahun wipe, Kini mbẹ ninu aha ti o nho yaya bayi? Ha! iwọ lo nho yaya yi, Kinla! Irẹtẹ ọkanran Awo ko mu loni o

Ọrunmila joko ti wọn ko fi ẹnu kan ohun kan nigbati o ṣe nwọn tun gbe ọti siwaju rẹ. Ọrunmila tun wi bakanna, ko si muu. Lẹhin ti awọn jẹ, ti nwọn mu tan, Ọlọfin wa tẹ Ifa si'ẹ, o ni ki awọn Awo Ifẹ ba on wo o, ki amodi ti o nṣe ọmọ on le fuyẹ. Nitoripe gbogbo awọn ẹgbẹ Oṣegun ti ṣe ileri fun Ọlọfin pe ọmọ na ko ni ku bi koṣepe ki o ye.

Ọlọfin bere lọwọ Ọrunmila wipe, kini ohun ti o ri wi nipa ti ọmọ na Ọrunmila si dahun pe, ọmọ na, yio ku, ayafi bi Ọlọfin ba le fi aṣọ igunwa rẹ, ati ẹni ori itẹ rẹ rubọ. Inu Ọlọfin dun nitori o ti nwa ọna lati fi pa Ọrunmila tẹlẹ, o wipe, ẹhẹn, ọwọ tẹ wayi, o sọ bẹ sinu. O mu eso werepe, o da a sara aṣọ, o da a sori ẹni, o ko awọn nkan na wa fun Ọrunmila.

Bi Ọrunmila ti tẹwọ gba a, bẹni ẹiyẹ kan nke si i wipe, Ọrunmila! maṣe joko lori ẹni loni, maṣe fi aṣọ bora loni, joko silẹ ilẹ, joko silẹ. Ọrunmila wa ke si Ọlọfin wipe, bi ko ba fẹ ki ọmọ na ku, kio tẹ ẹni na, ki o joko le, ki o si fi aṣọ na bora.

Ọlọfin ko fẹ ki awọn enia mọ wipe jamba ni On ṣe fun Ọrunmila, o ni ki awọn Babalawo yoku fi aṣọ na bora. Nigbati nwọn ṣe bẹ tan oro mu gbogbo wọn, nwọn nyira nilẹ ninu ile Ọlọfin. Ọrunmila dide jẹ o kọri si ile rẹ ni alafia.

Ọrunmila wa bẹrẹ si wi bayi wipe, Eke yio pa, eleke, ọdalẹ yio pa ọdalẹ, awọn lo difa fun Amokun-ṣole ti o wipe, ọba aiye ko ri on. Njẹ bi ọba aiye ko ri ọ, Ọba ọrun ko ha nwo ọ ndan? Ọbara-wofun.

## Igbimo Ibadan Gba Ero Lati Da Owo Awon Oloye Duro

IBADAN Ipade ti awọn Olugbimọ ilu Ibadan ti iṣe ẹgbẹ N.C.N.C. ṣe kọja ni ọjọ Satide ni nwọn ti fi ohun ṣọkan lati da owo-oṣu awọn Oloye duro nitori aiko wa si Ipade Igbimọ dede awọn Oloye na, ati pẹlu wipe awọn Oloye na ki i ba awọn Igbimọ ṣepọ

Kansilọ Yinusa Ọladọja ni a gbọ wipe o da imọran na ti o si sọ wipe awọn Oloye na ki i wa si Igbimọ dede papa Ọba Olubadan. Nwọn ni o si tu sọ wipe gbogbo Igbimọ kekeke to wa ni agbegbe ti o ti ri wipe awọn oloye ti ilu wọn ko ṣe dede bẹ ti da seria fun wọn ti Ijọba Iwọ-Orun si gba bẹ la'si ani-ani, Ijọba yio gba fun wa.

No. 73/S. 2./Vol. V/963.

## Royal Routes In Ibadan

The following routes will be used by the Royal Party during the Visit of Her Majesty the Queen to Ibadan:

SATURDAY, 11th FEBRUARY

(a) ARRIVAL AT IBADAN BY TRAIN: Ibadan Railway Station to Government House Via Dugbe, Ekotedo, Mokola and Hammock Road.

(b) OFFICIAL RECEPTION AND INVESTITURE: direct route to the Western Hall from Government House. Return by the same route.

SUNDAY, 12th FEBRUARY.

Free Day.

MONDAY, 13th FEBRUARY.

(a) RALLY AT THE RACECORUSE: Government House to Racecourse via Hammock Road, Mokola and Saben Gari.

(b) MOOR PLANTATION: from the Racecourse via Stones Road, Dugbe and Lagos Road to Moor Plantation. Return via Railway Station, Dugbe, Ekotedo, Mokola and Hammock Road.

TUESDAY, 14th FEBRUARY.

VISIT TO FEDERAL INSTITUTIONS OF HIGHER LEARNING: Goverement House Via Hammock Road to University College Teaching Hospital; thence via Mokola and Oyo Road to the Nigerian College of Arts, Science and Technology, thence to the University College via Oyo Road. Return to Government House via "Aerodrome Road" (Bodija Crossing).

WEDNESDAY, 15TH FEBRUARY.

(a) OPENING OF NEW PARLIAMENT BUILDING: Government House via Hammock Road to Bunny's Leap, thence via the new dual carriageway direct to Parliament Building. Return to Government House through Agodi – shortest route.

(b) DEPARTURE FOR IJEBU-ODE: from Government House to Taffy Highway then via Bere Square and Mapo Hall, down Isale Ijebu and thence to the Ibadan - Ijebu-Ode Road.

Maps shewing the Royal routes for each day will be included in the Official programme which will be published in due course.




**E Ka Iwe Irohin Eleti-Ọfe Fun Irohin Aladun**

## Aro Eyo Adamorisa

A gbiyanju tẹ Aro Ẹyọ Adamuorişa niwọnba şoki fun anfani ẹnyin ọkawe wa

1. Hu-u-haha, mo yọ fun ẹ, mo yọ fara mi hu-u-haha.
2. Emi aboju pa a, emi aboju po o, emi aboju b'ọ ọ lẹru bi arọni hu-u-haha
3. O şe mi tibalaka, tibalaka, o şe mi tiboloko, tiboloko ẹniti o lado do ejo ni yio han, ni mọdẹ irayc hu-u-haha.
4. Igba funfun leremi, ẹni ba mọ wẹ ko lọ mu hu-u-haha
5. Bi o balẹ, bi o balẹ ni labalaba şe nwọ igbo, Arabalẹ ni ti Awodi hu-u-haha.
6. Aşaşa winrin, aşaşa winrin ẹwọn balẹ ro wọrọ-iọ hu-u-haha.
7. Lọjọ ti awọn Akala, nkala laroko nro oko, ti Ayẹna nyẹ ọna hu-u-haha.
8. Aroko ku, a sinku aroko, ayẹna ku, asinku ayẹna, Awo lo ku loni ti a nsin awo, ni mọdẹ irayi hu-u haha.
9. Inunurin lawo inunurin, Alakiasa lawo ilasa Ti o da fun Alayun Ayunrẹ ti orişa nyọ fun loni hu-u-haha
10. Aja fi mimi sukun ọsọrọ balẹ ro pọ, hu-u-haha.
11. Akala wọle Ọjọra, Erikina wọle Adam'orişa fo rabata wọ ilẹ Olokun. hu-u-haha.
12. Tintin lo nşawo ode tintin Okuta nla şele gbarago ni mọdẹ irayc. hu-u-haha.

## Ilu Ibini Nse Ipalemo Ati Gba Alejo Nla

BENIN-CITY - Nitbati Alaiyeluwa Ọba Obinrin pẹlu ọlọla nla ọkọ rẹ ba de ilu Ibini ni ọjọ kẹfan oşu Febuary, 1956, gẹgẹbi eto ti awọn ti şe, aye pataki ti awọn ọmọ ile ẹkọ yio duro, ni nwọn ti nşe atunşe rẹ silẹ.

Aye na yio gba awọn ọmọ ile ẹkọ bi ẹdẹgbarin enia, nibẹ ni oju ọna ti Alaiyeluwa ati ọkọ rẹ yio gba ni ọjọ nla na. Koda, ipalẹmọ ti ilu Ibini nşe na yio kẹ - riri.

## Kini ohun ti oju ko riri

Awọn ti ki işe Yoruba npete nisisiyi lati jo ijo aramọda kan han Ọba obinrin ti o mbọ yi. Nwọn sọ wipe ẹnikan koiti jo irufẹ ijo bẹ ri.

Emi rope ko si ere kan ti o le bori ere Gẹlẹdẹ ati ere Adam'orişa Gẹgẹbi ọrọ na ti ta si wa leti, ere mẹta pataki ni agbọ wipe awọn ni ara Eko lẹ şe fun Ọba obinrin ti o mbọ na. (1) Nwọn fẹ şe ere Ẹyọ (2) Ere Gẹlẹdẹ (3) ati ere Wọrọ.

POLOWO
ỌJA RẸ
SINU IWE
IROHIN
ELETI - ỌFẸ



## Adajo Ko Ti Olugbimo Kekere Mole

EKO- Oloye Ọlọla O. Oweh ti a ṣe irohin nipa ẹjọ ofin Mọto ti a gbọ pe nwọn fi sun ẹsun rẹ, ni a tun gbọ wipe Adajọ Ọgbẹni R.O. Gaji da silẹ ti o si sọ wipe on ko ti Oloye na mọ'le gẹgẹbi Iwe Irohin kan ti sọ.

Bi ọrọ ti ri ni yen o. Ọlọ'a Oloye Oweh j'are, Adajọ si da silẹ ki o ma lọ ni alafia.

Lọya Adeniran Ogunsanya ni o ṣe ẹjọ Oloye Oweh.

## IYA MỌMU K'OGUN NI ỌDUN TUNTUN

EKO- Agbako Ori ẹdẹ, Oluwa majẹ ki a rin ni ọjọ ti ebi npọ'na, Egbao amin koto. Eleyi, niwọn'ba ṣoki ni irohin kan ti a gbọ lati opopo Ẹhin-Ọgba ni owurọ ọjọ Jimọ (Friday) ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu January, 1956.

Obinrin kan ti nwọn npe ni Iya Mọmu ti o nta aṣọ Gele ni Ẹhin-Ọgba, ninu ọsẹ to kọja le yi ni o se gbolohun aṣọ pẹlu Arabinrin aboyun kan ti o nta Wesiwosi ni ẹgbẹ iṣọ re, ede-aiyede yi pọ tobẹ gẹ, ti awọn eni meji yi fi ta lu arawọn.

Ni ọjọ kẹta ni a gbọ wipe aboyun gb'ẹru o re ọrun alakeji, ọrọ wa di ṣawura, irohin yi ni awọn ọlọpa gbọ ti wọn lọ fi ra Iya Momu mu, nwọn gbe ju sinu Mọto wọn, ọrọ di Ita Tinubu.

Ọrọ re o, ẹnyin arija gba!




## ORIKI BAMWO

Bamwo de,, alajẹla ọmọde, agb'ọmọla bi oriṣa, akọkọluko ogun nda'mọ l'ẹkun igbona, atata ogun ti np'otutu rẹ warawara, a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abiku dikugbagbe, o ṣ'ọmọ ti nhehin l'ore, Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aiperi ri i d'ẹkun iyọnu. Olugbala f'ọmọ ti nyagbẹ ọrin, o kapa inu iwọ, o ln jẹdi l'alupa, gbogbo abiyamọ nyọ ṣẹṣẹ. Ela ri i o roju, Ọrẹrẹ ri i o na'gbẹ bo'ra. Ẹyi npa'lẹmọ lodilẹsọ, Ọrẹ ikoko, koṣemani awọn abiyamọ, ẹni araiye njijadu ra.

O de'lu Ibo, o dọ'ga, o de'lẹ Hausa, o d'ọba. Gbogbo Onisegun l'o sọ pe ko l'ẹgbẹ, gbogbo ọmọde l'o nfẹ ẹ fun'lera.

IGO KEKERE 2/6d.
IGO NLA 4/6d.
owo ọkọ 1/6d fun igo kan.

THE ẸGBA TRADING ARADAN STORES
18, Denton Bridge Street,
P. O. Box 2,
Ebute-Mẹta.



## ILE ỌLA, AGBALA IGBADUN YARA-FUNFUN BUCKINGHAM PALACE

Aworan apakan ninu yara to mọ ni'le ọla, agbala igbadun ti a npe ni Buckingham Palace nilu oyinbo Gẹsi, ti iṣe ibugbe awọn ọba ni ẹ nwo yi.

Irufẹ ile bẹ ṣ,ọwọn l'orilẹ aiye.

## ỌBA ADELE NI YIO GBA ỌBA OYINBO LALEJO

(O bẹrẹ loju ewe keji)

Nigbati o ba de Yaba (Round About) yio fi iyoku le ọba Adele lọwọ. Adele yio ṣe si nibẹ bi o ba se tan, awọn "We yọ mirọ" yio tun lẹ siwaju, ọba yio tẹle wọn lẹhin, lẹhinna Adele yio tẹle.

Nwọn o gba opopo Clifford Street, Denton St Ọtọ ati Iddo, o di ori Kereni lọ si Idumọta, gba Kreko St, Balogun St Broad Street, Tinubu Sq, Customs St ja si opopo Ehingbeti lọ si Ile Ọba. Bayi ni Ọba yio rin lọjọ ti o ba kọkọ de si ilẹ wa.

## Moto Alaiyeluwa Rolls-Royce

Aworan awọn Mọto Ayọkẹlẹ ti gbogbo ara re ie igbadun, ti inu rẹ kun fun igbadun afẹfẹ to minringindin ti Alaiyeluwa Ọba Obirin pẹlu ọkọ rẹ Ọlọla nla Duke of Edinburgh, yio lo ni gbogbo asiko ti awọn ẹni-Ola nla na yio fi ṣe abẹwo ilu Nigeria wa yi.

Aworan Ọgbẹni Garner ti ile iṣẹ Rolls-Royce ni o mbẹ lara esẹ awọn Mọto ayọkẹlẹ na, on si ni ẹni ti yio wa Mọto Ọba na nilu Eko.

Kabiyesi o, Ọba alaṣẹ ekeji Oriṣa!



Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 25 Kosoko Street P.O. Box 407 Lagos Phone 22378